BON SECOURS HEALTH SYSTEM

**Eto imulo/Ilana**

| | | | |
|---|---|---|---|
| Akọle: | Iranwọ owo Alaisan | Ọjọ:<br><br>Ọjọ Irọpo Ẹya: | Ọjọ Keji Osu Keji Ọdun 2019 |
| Ẹya: | SYS.FIN.BILL | Ẹni ti o fiọwọsi:<br>Awọn ajọ<br>BSHSI | |

## ETO IMULO

O jẹ eto imulo ti awọn Bon Secours Health System, Inc. ("BSHSI") lati alaye to niṣe pẹlu sisan owo ati gbigba owo fun BSHSI ni awọn ile-iwosan nla. Ajọ BSHSI ti ṣe ifarajin lati rii daju wipe eto ilera pipe fun gbogbo eniyan. BSHSI nṣe itọju fun gbogbo awọn alaisan, boya wọn ni eto adojutofo abi wọn ko ni, pẹlu iyi, ibọwọ fun ati aanu lati ibi igbaniwọle, ọna ti a n gba ṣiṣẹ, ida alaisan silẹ, ati ilana sisan ati gbigba owo. Eto imulo yi di kikọ pẹlu ero ngba lati ṣe itẹlọrun fun awọn ibeere ni abala 501(r) koodu awọn ajọ ti n pawo wọle labẹnu ti ọdun 1986, eyi ti o ni ṣe pẹlu ṣise iranwọ ati itọju pajawiri, dindin owo sisan ku fun awọn eniyan ti o tọ lati gba iranwọ owo, ati gbigba owo ni iwọnba ati akitiyan gbigba owo ati lati se atupalẹ rẹ bi o ti yẹ.

## AFOJUSUN

Eto imulo yii yio jẹ lilo fun itọju pataki BSHSI, ati fun awọn ohun elo ti yara pajawiri. Akọsilẹ fun gbogbo awọn ohun elowa ni opin eto imulo yii. Eyikeyi ile-iṣẹ igbowo ti o nṣiṣẹ bi asoju ajọ BSHSI yio bu ọla fun ati ṣiṣe atilẹyin awọn gbigba owo awọn iṣẹ BSHSI gẹgẹbi a ti ṣe alaye ni isalẹ. Ayafi ti o ba jẹ bẹẹkọ ni pato, eto imulo yii ko kan awọn onisegun tabi awọn osiṣe ilera, pẹlu ṣugbọn kii ṣe fun awọn oniṣegun yara pajawiri nikan, awọn Olurapada, oṣiṣẹ ọkan, Ile-iwosan, ati alayẹwo ẹjẹ.

## ERONGBA

Erongba fun eto imulo yii ni fun ajọ BSHSI lati gba owo lọwọ awọn oniduro ati ẹni ti o tọ lati sanwo, ni akoko, ati ni ibamu pẹlu awọn ofin ati ilana ti o yẹ.

Ajọ BSHSI ati eyikeyi ile-iṣẹ igbowo ni yio rii daju wipe awọn iṣẹ ti wọn pese wa ni ibamu pẹlu gbogbo ofin Ijọba apapọ, ipinlẹ ati ofin abẹle, ofin ati ilana to n dari iṣẹ, pẹlu Ilana agbekale gbigba owo lona ti ko nira (FDCPA). Ni awọn adehun rẹ pẹlu ajọ BSHSI, Ile-iṣẹ oluranlowo gba owo kọọkan yio ni lati ṣe itọju gbogbo awọn alaisan, awọn agbani ṣiṣe ati awọn alabaṣepọ iṣẹ ni ibamu pẹlu afokansun ati iyebiye Bon Secours Health System. Siwajusi, Igbimọ Ile-iṣẹ Ibanigbowo kọọkan yio fi aṣẹ si wipe oun yio lo awọn liana iṣẹ ti o dara julọ ni ṣiṣe Awọn iṣẹ naa.

Ajọ BSHSI ni yio igbiyanju lati ṣe daju pe alaye nipa eto iranlọwọ owo ati wiwa rẹ yio han daju gbangba ati ki o si wa larọwọto fun gbogbo eniyan. Ibeere fun iranlọwọ Owo wa ati eto imulo, akọsilẹ ede pipe, ati Ilana Isanwo ati igbowo owo wa fun wiwo tabi gbigba ni www.fa.bonsecours.com. Ti ẹ ba beere, awọn eniyan yio pese, ẹda iwe ibeere fun iranlọwọ owo ati eto imulo, akọsilẹ ede pipe, ati Ilana Isanwo ati igbowo lai si idiyele lori rẹ. Ti ẹ ba beere, ajọ BSHSI yio pese adirẹsi aye ayelujara Iranlowo owo wa.  Olukuluku le ri iranlọwọ gba ti wọn fi owo si iwe ibeere fun iranlọwọ owo ni eyikeyi awọn agbegbe iforukọ silẹ, awọn olubadamọran owo, tabi awọn ọfiisi igbowo owo wa. Awọn olubadamọran owo tabi awọn ọfiisi isanwo wa ni agbegbe iforukọsilẹ awọn alaisan. Olukuluku le duro ni eyikeyi awọn ibudo alaye wa ti o wa laarin ile-iwosan kọọkan lati beere fun iranlọwọ ni wiwa awọn alamọran owo wa ri tabi ọfiisi. Isanwo wa. Olukuluku le gba ẹda iwe ibeere fun iranlọwọ owo ati eto imulo, erefe ede geere ati Ilana Aṣayan Isanwo ati igbowo kan lọfẹ, nipasẹ erọ ayarabiaṣa, ati nipasẹ pipe ẹka iṣẹ onibara wa ni (ibilẹ) 804-342-1500 or (Ipeọfẹ) 877-342-1500.

## AWỌN ITUMỌ

Iye owo Sisan ni kikun (AGB) –Iye owo Sisan ni kikun tumọ si iye owo ti won ni ki awon alaisan san fun pajawiri ati sise itọju ti o yẹ fun awọn ti o ni eto adojutofo fun iru itọju naa.  Idiyele fun awọn alaisan ti wọn kun oju osunwo fun iranwọ owo ko ni san kọọja iye ti a n gba lọwọ gbogbogbo ("AGB") fun iru itọju bẹẹ.  Awọn idiyele wọnyi da lori apapo iye owo ti a gba laaye fun ilera ati awọn onibara ti yio sanwo fun pajawiri ati awọn itoju miran ti o yẹẹ. Iye owo ti a gba laaye ni apapo iye owo ti ile ise adojutofo ati iye owo ti o ba di dandan, ti eniti n gba itọju yio san. Ilana atunyẹwo lat'eyin ni a fi n ṣe iṣiro AGB fun 26 CFR kan §1.501(r), eyi ti o le e tunṣe loorekoore. Wo ATỌKA A fun alaye siwaju sii fun edinwo lori AGB.

Ile-iṣẹ Abanigbowo "Ile-iṣẹ Abanigbowo " jẹ eyikeyi ile-iṣẹ ti awon ile-iwosan nlo lati lepa tabi gba owo lọwọ awọn oniduro.

Akoko Iwe Ibeere - Akoko Iwe Ibeere  fun awọn oniduro lati beere fun iranwo owo bẹrẹ lẹhin ọjọ akọkọ gbólóhùn ìdíyelé ti yio si pari lẹhin 240 ọjọ lẹhin ọjọ akọkọ gbólóhùn ìdíyelé tabi o kereju lẹhin 30 ọjọ lẹhin ti ajọ BSHSI ipese oniduro kan pẹlu akọsilẹ ti o ni gbedeke lẹhin eyi ti ECA (s) ni a le e pilẹṣẹ.  Ti a ba ti fọwọsi iranlọwọ owo fun alaisan, akoko gbedeke naa yio jẹ 240 ọjọ ṣaaju lori gbese ti o ṣe gba ati akọọlẹ owo ati 240 ọjọ ti o ti fi ọwọ si iwe-ibeere wọn pelu ọjọ. Awọn alaisan ti a fọwọsi fun iranwo owo ti o pada wa fun eto ni akoko itẹwọgba wọn ti o jẹ 240 ọjọ a yio ṣe ayẹwo eto adojutofo ilera won, ipinle tabi ibilẹ ni akoko ibewo kọọkan. Eto iranlọwọ owo Ajọ BSHSI kii ṣe adojutofo.

Imudaniloju Iranlọwọ owo - Nigba ti eniti o jẹ alaini adojutofo ba le farahan pe oun yẹ fun iranwlọwọ owo ṣugbọn ti eni naa ko pese awọn iwe atilẹyin ti o nilo lati fi idi irufẹ amuye bẹẹ lelẹ. Ni awọn igba wọnyi apapọ owo-ọya alaisan ati / tabi Iye owo Ipele Osi ti Ijọba Apapọ ni a le pese nipasẹ awọn orisun miiran, gẹgẹbi awọn ile-iṣẹ gbese, ti yio pese awọn ẹri ti o to lati ṣe alaye lori alaisan pẹlu iranwo owo. Erongba imuyẹ da lori ipinnu nipasẹ isele si isele ati wipe o munadoko fun itọju ni akoko naa.

Igbese Gbigbagbese L'ọnara (ECA) - ECA, gegebi liana IRS, je ọkan ninu awọn wọnyi:

- Tita gbese ẹnikan fun ẹlomiran

- Gbigbe ọrọ naa lọ siwaju awọn ajọ ti n ba ni gba gbese tabi awọn ile-ise gbese
- Kikọ jalẹ, yiyari tabi bibeere owo ṣaaju ki a to pese itọju ailera ti o yẹ nitori aisan gbese ti tẹlẹ
- Awọn igbeṣẹ ti o la ilana ofin, pẹlu ṣugbọn eyi ti ko ni gbedeke fun:
    - Gbigbe ipolowo lori ohun ini
    - Gbigbẹsẹ le ohun ini
    - Sisomọ tabi gbigba akọọlẹ ifowo pamọ tabi ohun ini miiran
    - Gbigbe igbese ofin lodi si ẹni naa
    - Fifi ofin gbe ẹni naa
    - Mimu ki ẹni naa wa labẹ abojuto ofin nipasẹ ẹrọ ti asomọ lara
    - Ṣiṣe itọju owo-oya awọn ẹni naa

Kikede ailowo lọwọ kii ṣe ECA.

<u>Oniduro</u> – Alaisan, olutọju, tabi ẹni ti o lẹto lati sanwo itọju ti alaisan naa gba ni akoko aisan.

<u>Eto Iranlọwọ Owo Fun Alaisan (FAP)</u> - Eto ti a gbe kalẹ lati ṣe adinku iye gbese oniduro jẹ. A gbe eto yii kalẹ lati fun awọn oniduro ti ko ni adojutofo ati fun ẹniti sisanwo ni kikun tabi diẹ-diẹ fa ipalara eto isuna wọn.

<u>Igbalaaye ECA</u> - Ṣugbọn awọn iṣẹ ṣiṣe ti o gbooro ti pin bi ECA, ECA BSHSI nikan ti yio jẹ ṣiṣe ni fifi ẹjọ sun awọn ajo gbese gbigba tabi awọn ile-iṣẹ gbese, bi o tiṣe pataki.

<u>Eni Ti O Yẹ lati Sanwo</u> – Ajo ti o yatọ si alaisan (ẹni akọkọ) tabi olupese ilera (ẹni keji) ti o lowo ninu sisanwo eto ilera ara rẹ.

<u>Adojutofo to mẹẹhẹ -</u> ẹniti ti o ni adojutofo ṣugbọn ti o jẹ wipe o n sanwo fun awọn ohun ti ko jẹ gbadun rẹ ni ibamu pẹlu eto anfani wọn. Awọn apẹẹrẹ ti o wa pẹlu ṣugbọn kii ṣe gbedeke si: Eto ilera lilo oògùn lai gba'se, bi a ti de gbedeke anfani, awọn oluranlọwọ ibi igbẹbi, ati bẹbẹ lọ.

Alaini Adojutofo – Alaisan ti ko ni adojutofo.

**ILANA**

<u>Awọn Alaye ti a Ṣeto</u>
Awọn oniduro le e beere fun awọn alaye ti a ṣeto eto isuna wọn nigbakugba laisi idiyele.

<u>Ariyanjiyan</u>
Eyikeyi oniduro le ṣe ariyanjiyan lori ohun kan tabi idiyele lori owo sisan wọn. awọn oniduro le bẹrẹ ariyanjiyan ni kikọ tabi lori foonu pẹlu aṣoju ile-iṣẹ onibara wa. Ti oniduro ba n beere awọn iwe-aṣẹ nipa owo sisan wọn, awọn ọmọ oṣiṣẹ yio lo gbogbo igbiyanju ti o tọ lati pese awọn iwe-aṣẹ ti oniduro naa beere fun ni aarin ọjọ mẹta.

<u>Akoko Owo Sisan</u>

Akoko owo sisan ti ajọ BSHSI beere lati ọjọ ti ẹ ti gba iwe alaye akọkọ. Ajọ BSHSI n gbiyanju ti o yẹ lati pe akiyesi oniduros nipa (FAP) wa ati bi wọn ṣe le e ri iranwọ gba lati yanju iwe ibeere fun iranlọwọ owo. Ni akoko owo sisan oniduro le gba ipe, iwe alaye ati

awọn lẹta lati lepa awọn akojọ ati lati ṣe iranlọwọ fun awọn oniduro nipa eyikeyi ibeere lori FAP. Ajọ BSHSI ṣe afikun lori alaye owo sisan kọọkan ati awọn lẹta lori liana owo sisan, ọna lati sanwo, iranlọwọ owo, ayelujara ati nọmba ile-iṣe onibara rẹ.

Iṣeto awọn laye ati awọn lẹta wa ni isalẹ:

- A fi iwe alaye ranṣẹ si oniduro nigbati a ba woye wipe o dabi enipe oniduro ba jẹ gbese silẹ
- A o tun fi lẹta miran ransẹ 30 ọjọ lehin ọjọ ti o wa lori iwe alaye ti a fi ranṣẹ si Oniduro wipe akoko ati sanwo ti to o si ti kọja pelu
- A o tun kọ lẹta keji ransẹ 30 ọjọ lehin lẹta akọkọ ti a fi ranṣẹ si Oniduro wipe akoko ati sanwo ti di aigbọran
- A o tun kọ lẹta kẹta eyi ti o jẹ igbẹyin ransẹ 30 ọjọ lehin lẹtakeji ti a fi ranṣẹ si Oniduro wipe akoko ati sanwo ti di aigbọran gidigidi ati wipe a le e gbe iwe owo ranṣẹ si awọn ajọ ti n gba gbese
- Ni 120 ọjọ ti akoko isanwo fun oniduro ti kọja a gbe iwe owo wọn lọ si ọdọ awọn ajọ ti n gba gbese akọkọ ti oniduro ko ba sanwo ti o jẹ ti a ko si gba iwe ibeere fun iranlọwọ owo lati ọdọ oniduro naa.
- Ni 300 ọjọ ti akoko isanwo fun oniduro ti kọja a gbe iwe owo wọn lọ si ọdọ awọn ajọ ti n gba gbese keeji ti oniduro ko ba sanwo ti o jẹ ti a ko si gba iwe ibeere fun iranlọwọ owo lati ọdọ oniduro naa.
- Ni 480 ọjọ ti akoko isanwo fun oniduro ti kọja a gbe iwe owo wọn lọ si ọdọ awọn ajọ ti n gba gbese to gaa julọ ti oniduro ko ba sanwo ti o jẹ ti a ko si gba iwe ibeere fun iranlọwọ owo lati ọdọ oniduro naa.

<u>Igbese Gbigbagbese L'ọnara</u>

Ajọ BSHSI ati awọn ile-iṣẹ ti n ba wọn gbowo le e ṣe ECA nipa gbigbe ọrọ naa lọ si ọdọ ajọ a gba gbese. Ajọ BSHSI ati awọn ile-iṣẹ ti n ba wọn gbowo ko ni ṣe ECA lodi si oniduro naa lai ṣe wipe wọn gbiyanju lati mọ boya oniduro naa yẹ fun iranlọwọ owo. Ni Pato oniduro naa yio:

- Gba ifilọ ni kikọ lati ọdọ awọn ajọ ti n gba gbese 30 ọjọ siwaju ECA.
- Gba ifilọ siwaju ọjọ ti ECA yio pilẹṣẹ.
- Gba ifilọ lati jẹ ki o mọ wipe iranlọwọ owo wa fun awọn eniyan ti wọn kun oju oṣuwọn.
- Gba ẹda alaye ede ni ṣoki gba fun FAP.

Awọn alabaṣepọ ajọ BSHSI yio gbiyanju lati ṣalaye lekunrẹrẹ fun oniduro nipa FAP ati bi wọn ṣe le gba iranlọwọ owo. Oniduro naa yio ni gbedeke 30 ọjọ lati beere fun iranlọwọ owo lẹyin igbati ajọ ti n gba gbese ba fi iwe ṣọwọ si nipa gbedeke ojo ti ECA yio bẹrẹ.

<u>Kosi ECA Ni Akoko Ti Ayẹwo Lọ Lọwọ Lori iranlọwọ owo</u>

Ajọ BSHSI ati igbati ajọ ti n gba gbese ko ni lepa ECA lori oniduro ti o ti fi iwe ibeere iranlọwọ owo ṣọwọ. Ti o ba jasi wipe oniduro naa yẹ fun iranlọwọ owo ati pe o oniduro naa ba ti sanwo, BSHSI yoo ṣayẹwoi lati ṣe ri daju pe boya iwe owo miran wa, ti o nii ṣe pẹlu oniduro naa, ni gbese a jẹ silẹ ti ko yẹ fun iranlọwọ owo. Ti iwe owo ti o jẹ gbese silẹ ba wa, ajọ BSHSI yio fi to oniduro naa leti, nipasẹ lẹta, lati sọ fun oniduro naa pe owo ti o san lori iwe owo naa, eyi ti o yẹ fun iranlọwọ owo, ni wọn yio gbe lọ sori iwe owo ti o jẹ gbese si. Ti oniduro naa ba kọ lati gbe lọ sori iwe owo naa, iye owo ti a ba gba ti jẹ deede

tabi ti o pọ ju $5.00 ni a yio da pada fun oniduro naa. Ajọ BSHSI ko owo ti o kere ju $5.00 lọ pada fun oniduro. Ti oniduro naa ba yẹ fun iranlọwọ owo ni iha kan gbese ti o ku ni a yio gbe sori akoko isanwo to n bọ. Ti o ba ṣẹ pe oniduro kọ iwe ibeere fun iranlọwọ owo ti wọn si ti fọwọsi fun erongba iranlọwọ owo, iranlọwọ owo naa yio jẹ ti saa oniduro naa lọwọlọwọ ati pe ko ni si owo dida pada ti tẹlẹ tabi owo dida pada lọjọ waju.

<u>Iṣeto Fun Iwe Ibeere Fun Iranlọwọ owo</u>

Ti eniyan ba fi iwe ibeere ti ko pari ṣọwọ ni akokoibeere naa, BSHSI yio:

- Fi to ẹni naa leti nipa kikọwe afikun alaye ti o nilo lati pari ibeere naa.
- Fi to ẹni naa leti nipa kikọwe wipe wọn ni 30 ọjọ lati fi afikun alaye ṣọwọ.

Ti eniyan ba fi ibeere to peṣọwọ ni akoko ibeere naa, BSHSI yio:

- Fi akọọlẹ naa si idaduro lati ṣe idiwọ fun gba ohunkohun titi ti a fi idi amuyẹ mulẹ.
- Ṣeto lori iwe ibeere naa ati gbiyanju gidigidi lati fi to ẹni naa leti nipa fifọwọsi laarin 60 ọjọ ti a ti gba iwe ibeere ti o pe.

Ti ẹni naa ba yẹ fun iranlọwọ owo iha kan, BSHSI yio pese awọn wọnyi:

- Lẹta itẹwọgba ti o fi ipele itẹwọgba iranlọwọ owo han ti iye ẹdinwo ti oniduro naa yio gba.
- Iwe alaye ti o ṣe afihan iye ti oniduro naa jẹ fun iṣẹ..

Ti eniyan ko ba fi iwe ibeere ṣọwọ ni akoko ibeere, oniduro yio gba iwe alaye ati lẹta ti o ni alaye nipa FAP. Ni igbiyanju lati gba owo fun iṣẹ ti a ṣe, BSHSI ati ajọ alabaṣiṣẹpọ wọn le ṣe ECA nipase gbigbe ẹlọ siwaju ajọ gbese. .

## ATỌKA A

AGB

Fun alaye siwaju sii nipa ẹdinwo AGB wa niwww.fa.bonsecours.com tabi nipa pipe ile-ise onibara wa ni (Ibile) 804-342-1500 or (Ipe Ọfẹ) 1-877-342-1500.  Fun ile-ise onibara ni Ile iwosan Gbogbogbo Rappahannock jọwọ pe 804-435-8529.

ATỌKA B

akojọ awọn Ile Iwosan

**Baltimore**

**Bon Secours Hospital**
2000 West Baltimore Street | Baltimore, MD 21223

**Hampton**

**Bon Secours Maryview Medical Center**
3636 High Street | Portsmouth, VA 23707

**Mary Immaculate Hospital**
2 Bernardine Drive | Newport News, VA 23602

**Bon Secours DePaul Medical Center**
150 Kingsley Lane | Norfolk, VA 23505

**Kentucky**

**Our Lady of Bellefonte Hospital**
St. Christopher Drive | Ashland, KY 41101

**Rappahannock**

**Bon Secours Rappahannock General Hospital**
101 Harris Road | Kilmarnock, VA 22482

**Richmond**

**ST. Mary's Hospital**
5801 Bremo Road | Richmond, VA 23226

**Memorial Regional Medical Center**
8260 Atlee Road | Mechanicsville, VA 23116

**Richmond Community Hospital**
1500 N. 28th Street | Richmond, VA 23223

**ST. Francis Medical Center**
13710 St. Francis Boulevard | Midlothian, VA 23114

**South Carolina**

**ST. Francis Downtown**
1 St. Francis Drive | Greenville, SC 29601

**ST. Francis Eastside**
125 Commonwealth Drive | Greenville, SC 29615

**ST. Francis Millennium**
2 Innovation Drive | Greenville, SC 29607